# Fi àwọn bátìrì o ní bọ́tìnì pamọ́ kúrò lọ́dọ̀ ọmọ ọ̀ rẹ

Tí ọmọ ọ̀ rẹ bá gbé bátìrì o ní bọ́tìnì mì, ó lè há mọ wọn lọ́fun. Ó lè jó lọ sí iṣọn ẹ̀jẹ wọn tí yóò pa wọ́n lára púpọ̀ tàbí pa wọ́n pàápàá.
Eléyìí lè ṣẹlẹ̀ ní kíákíá.




Àwọn ọmọdé tí ọjọ́ orí wọn wà láàárín oṣù 6 sí ọdún 4 ½ wà nínú ewu jùlọ.

## Àwọn bátìrì wo ni ó léwu jù?

Àwọn bátìrì sẹ̀ẹ̀lì owó lithium tóbi díẹ̀ ju ẹyọ 5 pence lọ. Wọ́n tóbi tó láti dúró wọ́n sì lágbára tó láti pa.

Àwọn bátìrì o ní bọ́tìnì kékeré ṣì lè fa ìpalára, pàápàá jùlọ tí wọ́n bá jẹ́ tuntun.

## Níbo ni wọn wà?

Ọmọ ọ̀ rẹ lè rí àwọn bátìrì o ní bọ́tìnì nínú àwọn nǹkan bíi:

- àwọn ohun tí a fi ńṣe àkóso látọ̀nà jíjìn kékeré
- àwọn ojú kọ́kọ́rọ́ ọkọ̀ tàbí ohun tí a fi ńwá kọ́kọ́rọ́
- àwọn káàdì orin àti àwọn ìwé
- àwọn nǹkan ìṣeré tó ń tan ná àti àwọn ohun èlò tuntun
- àwọn iná alẹ́
- àwọn ọ̀ṣùwọ̀n o ní díjítà
- àwọn ọ̀ṣùwọ̀n ìgbónà
- àwọn nǹkan ìṣeré àtijọ́ nínú àpótí rẹ̀

Àwọn ọmọdé tún lè rí àwọn bátìrì tí wọ́n fi pamọ́ sí àrọ́wọ́tó tàbí tí wọ́n ti jábọ́ láti inú ìdì wọn.

Kódà àwọn bátìrì 'tí kò ṣìṣẹ́ mọ́' tí wọ́n ti lò ṣì ní agbára tíó tó láti léwu.

## Yẹ ilé è rẹ wò

- Ṣe ọdẹ yíká ilé è rẹ fún àwọn bátìrì o ní bọ́tìnì
- Tọ́jú àwọn ọjà dáradára kúrò ní àrọ́wọ́tó ọmọ rẹ tí ìyẹ̀wù bátìrì kò bá ní ààbò
- Fi àwọn bátìrì tó ṣẹ́ kù àti àwọn 'tí kò ṣìṣẹ́ mọ́' pamọ́ dáradára kúrò ní àrọ́wọ́tó pẹ̀lú
- Ṣọ́ra fún àwọn ìdúnàádúrà láti ọjà orí ayélujára tàbí àwọn ilé ìtajà ẹ̀dínwó ìbílẹ̀. Wọ́n lè ní bátìrì o ní bọ́tìnì tí ọmọ rẹ lè mú nírọ̀rùn.

## Ṣé ọmọ rẹ ti gbé ọ̀kan mì bí?

- **Má ṣe pẹ́. Mú wọn tààrà lọ sí A&E tàbí pe 999 fún ọkọ̀ aláìsàn.**
- **Sọ fún dókítà pé o rò pé ọmọ rẹ ti gbé bátìrì bọ́tìnì mì.**
- **Bí o bá ní àkójọ bátìrì tàbí ọjà tí bátìrì náà jáde láti inú rẹ̀, mú u lọ́wọ́ pẹ̀lú rẹ.**
- **Má ṣe jẹ́ kí wọ́n jẹun tàbí mu, má sì jẹ́ kí wọ́n ṣàìsàn**

**Àwọn àmì díẹ̀ lè wà.**
**Nítorí náà gbẹ́kẹ̀lé ìmọ̀ ọkàn rẹ.**

capt.org.uk/button-batteries
@ChildAccidentPreventionTrust

child accident prevention trust